**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

# Irohin Yoruba

NO. 127 WEDNESDAY DECEMBER 16 – TUESDAY DECEMBER 22 1964 KOBO META 3D

**Akiyesi**

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

IDURO KO SI O, IBẸRẸ *KO* SI O!

# AKINTỌLA GB'ODO MI



OLOYE ỌBAFEMI AWOLOWO

## 'Gbenro tu kẹkẹ ọrọ silẹ

**Ogunna-gbongbo iṣelu Ipinlẹ Iwọ Orun ti iṣe adele babasalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, Alhaji Dauda Adegbenro ti kesi Oloye S. L. Akintọla Olori ẹgbẹ NNDP lati sọ fun awọn ọmọ Yoruba ohun anfani kanṣoṣo ti ijọba rẹ ti ṣe si Ipinlẹ Iwọ Orun lati ibẹrẹ ọdun 1963 "ti Ijọba Balewa ti da pada sihin."**

Alhaji Adegbenro sọ pe kaka ki ọwọ ẹgbẹ Dọmọnu tun awọn ohun meremere Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe, nṣe ni ọwọ ẹgbẹ na nbaajẹ laibikita fun ohun ti awọn ... Ipinlẹ na ṣe.

O ... awọn ... Ipinlẹ yi ti awọn ti yipada si koto ṣe gegele re nitori aimojuto awọn alṣẹ.

Lori apakini Irin ajo rẹ kakiri Ipinlẹ Iwọ Orun ni Alhaji D S Adegbenro ti sọ ọrọ yi fun ẹgbaagbeje awọn ọmọ ẹgbẹ Itẹsiwaju ni Efọn Alaye ni agbegbe Ekiti ni ọjọ kedogun oṣu yi.

Alhaji Adegbenro sọ pe o to akoko fun awọn ọmọ Yoruba lati ronu pe awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu ko wa si Ipinlẹ Iwọ Orun lati tun ṣe sugbọn lati parun.

O sọ pe o yẹ ki o ya gbogbo enia lẹnu pe fun odidi ọdun meji ti awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu fi ṣe akoso ijọba awọn ko le da ọda si ẹyọ ibusọ kan pere tabi kọ ile iwosan kanṣoṣo si ibikibi ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

Larin igbe Awo! Awo! Alhaji Adegbenro sọ pe "Oloye Akintọla ti gbodo mi, ile ko gba mọ bẹẹl ọna ko si gba mọ

Wo Oju Ewe kẹjọ




## Awọn oṣiṣẹ dibo fun UPGA

Igbimọ gbogbo awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ Iwọ Orun (Western Nigeria Joint Action Committee 'JAC') ti sọ gbangban faiye gbọ pe ẹgbẹ Itẹsiwaju "UPGA" ni gbogbo awọn oṣiṣẹ yio di ibo wọn fun ati pe ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ si lati polowo Ibo karakara fun ẹgbẹ "UPGA"

Akọwe ẹgbẹ na, Ogbẹni E U Ijeh sọ ninu ikede kan ti o gbe jade ni Ilu Ibadan lẹhin ipade iwọn adọtalelugba awọn aṣoju ẹka ẹgbẹ na mejidinlogota ti nwọn ṣe ni ọjọ kẹwa oṣu kejila ọdun yi pe awọn ti ri mo daju pe ẹgbẹ UPGA ni ẹgbẹ ti eto oṣelu rẹ fihan pe yio ja fun awọn mẹkunnu awọn oṣiṣẹ ati pe nipa ayẹwo finnifinni ... ri ileri itura ti awọn ẹgbẹ iselu mejeji ti o fẹ fo ri gbari fun idibo ṣe fun awọn adibo o han kedere pe ẹgbẹ UPGA ni itara idagbasoke Orilẹede yi sọkan.

Igbimọ na si ti gbe aṣẹ fun akọwe ẹgbẹ na lati bẹrẹ si se asaju ipolowo idibo fun ẹgbẹ na.

Ninu ipade nla na, nwọn se ipinnu pe awọn ko nigbẹkẹle ninu apakan ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ eyiti Ogbẹni Vactentina Awah jẹ akọwe fun, ti o si tun jẹ ẹka fun ẹgbẹ Onirugbọn (Ẹgbẹ Otẹgbẹyẹ) "SWAFP". Nwọn ni apo kanna ni awọn ati ẹgbẹ Onikumọ

(Wo oju ew kẹjọ)

## *Akintọla fẹ ta apakan Yoruba* —Okpara

Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ti iṣe babasalẹ ẹgbẹ Alakuko, Dokita M. I. Okpara ti tu asiri adehun bonkẹlẹ ti o wa larin ẹgbẹ Dọmọnu ati ẹgbẹ Olomi ti Oke Ọya ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi pe ẹgbẹ Dọmọnu ti ṣe ileri "lati ta apakan nlau ilẹ Yoruba fun ẹgbẹ Olomi na."

Dokita Okpara ṣe alaye siwaju si pe ninu adehun abẹlẹ na, ẹgbẹ Dọmọnu ti ṣe ileri fun ẹgbẹ Olomi yi kanna pe on ki yio tun ṣe fun idapada igberiko Ilọrin ati Kabba ti nwọn jẹ ilẹ Yoruba tẹlẹ ri si Ipinlẹ Iwọ Orun mọ.

Dokita Okpara tu gbogbo aṣiri adehun na ni ilu Ogoja ni ọjọ na nigbati o nba ọpọlọpọ awọn enia ọrọ nibiti o ti ṣi ile ero kan ti nwọn fi bi ọkẹ marun pọnun kọ.

O fikun pe Oloye S. L. Akintọla faramọ gbogbo adehun na nitori ileri anan ti ẹgbẹ Olomi ti se fun un ni

Dokita Okpara wa pe awọn asaju ẹgbẹ mejeji na nisa pe ki nwọn sọ fa iye gbọ bi o ba se pe iru adehun bẹ ba wa tabi ko si.

Dokita Okpara wa se alaye bayi pe igbati awọn adibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun ba fi Ibo wọn le Dọmọnu lugbẹ ni alafia ati Igbadun yio to pada bọ si Ipinlẹ na.

### AKIYESI

ALALA kan ti tun de si Ibadan. Njẹ o ti gburo rẹ bi? Bi o ko ba iti gburo rẹ, On ni Woli Olu Amore. Ka ala rẹ lori Oloye Awolowo ni ọsẹ ti o mbọ. Tete ra tirẹ.

### Ogbomọṣọ pada

ASIRI ẹgbẹ Dọmọnu tu ni Ogbomọṣọ ni ọjọ kerinla oṣu yi nigbati Dọkita C O. Adeoye ati ọgbẹni M. A. Akande sọ fun Ipade awọn onirobin ni ilu na pe ẹgbẹ UPGA ni yio ko ijoko meji ti o wa fun ilu Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ ninu Idibo ti o mbọ yi.

Awọn aṣiwaju na tu asiri awọn iwa jamba ti ẹgbẹ Akintọla nhu ni ilu na. Ka Irohin yoku ni ọsẹ ti o mbọ.

**Gbadun Ẹmi ẹ pẹlu STAR**



